WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com

P3292 Nov.
WASSCE 2007
YORÙBÁ 2
Essay
2 hours

# 2

Name:....................................................

Index Number:....................................

## THE WEST AFRICAN EXAMINATIONS COUNCIL

### West African Senior School Certificate Examination

November 2007 | YORÙBÁ 2 | 2 hours

Essay

[ 100 marks ]

PÉPÀ 2

Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà

*Dáhùn ìbéèrè* **mẹ́fà** *lápapọ̀:* **mẹ́ta** *láti* ìpín A, **méjì** *láti* ìpín B *àti* **ọ̀kan** *láti* ìpín D.

www.myschoolgist.com



© 2007 *The West African Examinations Council*

**Turn over**

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com



## ÌPÍN A

## ÈDÈ

*Dáhùn ìbéèrè* **mẹ́ta péré** *nínú ìpín yìí.*

### ÀRÒKỌ/LẸ́TÀ

[ 25 marks ]

1. Kọ àròkọ tí kò dín ní **300** ẹyọ ọ̀rọ̀ lórí orí-ọ̀rọ̀ **kan ṣoṣo** tí o bá yàn. Máṣe lò ju **ìṣẹ́jú márùn-úndínláàádọ́ta** lórí abala yìí. Èdè Yorùbá ni kí o fi dáhùn gbogbo ìbéèrè kí o sì lo àkọtọ́ òde òní àti èdè-Ìperí Yorùbá.

   *(a)* Ènìyàn ṣòro

   *(b)* Pàtàkì ètò ìròyìn ní àwùjọ wa

   *(d)* Ìlù

   *(e)* Ìwúlò epo pupa

   *(ẹ)* Kọ lẹ́tà sí àbúrò rẹ tí ó wà ní òkè-òkun láti ròyìn ayẹyẹ ìgbéyàwó ẹ̀gbọ́n yín tí ó wáyé láìpẹ́ yìí.

www.myschoolgist.com

### ÈTÒ ÌRÓ

[ 15 marks ]

*Dáhùn ìbéèrè* **kan ṣoṣo** *níhìn-ín.*

2. *(a)* Mú **mẹ́ta** nínú àwọn ìró ìsàlẹ̀ wọ̀nyí; sọ ibi-ìṣẹnupè àti ọ̀nà-ìṣẹnupè ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

   (i) [ b ]

   (ii) [ f ]

   (iii) [ j ]

   (iv) [ n ]

   (v) [ w ]

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com



*(b)* Ṣàlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ẹ̀yà-ara-ìfọ̀ wọ̀nyí:

(i) tán-án-ná;

(ii) àfàsé;

(iii) ahọ́n.

3. *(a)* Kọ ọ̀rọ̀ **méjìméjì** tí a yá wọnú èdè Yorùbá nípasẹ̀ àwọn ìlànà wọ̀nyí:

(i) ẹ̀sìn;

(ii) ètò ẹ̀kọ́;

(iii) ọrọ̀ ajé;

(iv) ètò ìṣèlú;

(v) ogun.

*(b)* Kin ni mọ́fíìmù? Fi àpẹẹrẹ gbe ìdáhùn rẹ lẹ́sẹ̀.

www.myschoolgist.com

## GÍRÁMÀ

[ 15 marks ]

*Dáhùn ìbéèrè* **kan ṣoṣo** *níhìn-ín.*

4. Ṣèdámọ̀ ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí àwọn ọ̀rọ̀ tí a fàlà sí nídìí wọ̀nyí jẹ́.

(i) <u>Wàhálà</u> ọmọ náà ti pin mí lẹ́mìí.

(ii) Ọ̀rọ̀ owó ilé ẹ̀kọ́ <u>àwọn</u> ọmọ <u>wàhálà</u> mi púpọ̀.

(iii) Ìyá ìbejì kò <u>sùẹ̀gbẹ̀</u> tó bẹ́yẹn.

(iv) Àyè kò sí fún <u>sùẹ̀gbẹ̀</u> ní Èkó.

(v) Iṣẹ́ <u>gbájúẹ̀</u> ni Ṣọlá yàn láàyò.

(vi) <u>Gbájúẹ̀</u> kì í ṣe orúkọ <u>rere</u>.

 **Turn over**

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com



(vii) Kémọkémọ tí ó ń rìn ló yọ ọ́.

(viii) A ti mọ Adé mọ́ ìrìn kémọkémọ.

(xi) Ìdòwú ń rìn kémọkémọ.

(x) Jẹ́jẹ́ ni ọmọ Ọlọ́run ń ṣe.

5. Ṣe àyẹ̀wò gbólóhùn wọ̀nyí kí o sì dáhùn ìbéèrè tí ó tẹ̀lé wọn.

(i) Lọlá se àsè ọjọ́ ìbí.

(ii) Òfin tuntun de gbogbo olùdìbò ní ilẹ̀ wa.

(iii) Agbára wọn kò ká ohun tó ṣẹlẹ̀.

(iv) Ẹgbẹ́ wa yìí lè ra ọkọ̀ sí ibùdó ìgbafẹ́.

Kọ àpólà orúkọ inú gbólóhùn kọ̀ọ̀kan sílẹ̀ kí o sì sọ iṣẹ́ tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ṣe.

www.myschoolgist.com

## ÌPÍN B

## LÍTÍRÉṢỌ̀

*Dáhùn ìbéèrè* **méjì pẹ́ré** *nínú ìpín yìí.*

## LÍTÍRÉṢỌ̀ ÀTẸNUDẸ́NU

[ 15 marks ]

*Dáhùn ìbéèrè* **kan ṣoṣo** *nìhìn-ín.*

### ÌTÀN ÀRÒSỌ ÀBÁLÁYÉ

ÒJÓ, O.: *Ìjàpá Tìrókò Ọkọ Yánníbo*

6. "Ọgbọ́n tí Ìjàpá gbọ́n, ẹ̀yin ni yóò máa tọ ìgbín". Fi ìtàn "Ìgbín àti Ìjàpá" ṣàlàyé àkíyèsí yìí.

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com



## Ewì Àbáláyé

Abímbọ́lá, W.: *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún* (p. 1–51)

7. Tọ́ka sí àwọn ọnà-ìṣọwọ́lo-èdè inú àyọlò yìí:

*"Òfòfò níí pẹrú*
*Èpè níí polè*
*Ilẹ̀ dídà ní í pọ̀rẹ́ ...*
*A diá fún ọ̀kánlénú irúnmọlẹ̀*
*Níjọ́ tí wọ́n ń jà á rọ̀dọ̀ Olódùmarè*
*A jọ gbórí ilẹ̀*
*A jeku*
*A jọ gbórí ilẹ̀*
*A jẹja ...*
*Àṣẹ dọwọ́ ilẹ̀, a jọ mu".*

## Eré Oníṣe

Ògúnníran, L.: *Eégún Aláré*

8. Ṣe àlàyé bí Dáṣọfúnjó ṣe jẹ́ ọ̀rẹ́ tó ṣe é gbáralé.

## Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ

[ 15 marks ]

*Dáhùn ìbéèrè* **kan ṣoṣo** *níhìn-ín.*

## Ìwé Ìtàn Àròsọ

Òní, K.: *Ojú Rí*

9. Sọ̀rọ̀ lórí àlá òjò tí Ògúngbẹ̀mí lá pé ó pa òun àti bí àlá náà ṣe ṣẹ.





www.myschoolgist.com

WAEC Past Questions - Uploaded on https://www.myschoolgist.com



## EWÌ ÀPILẸ̀KỌ

ADÉBỌ̀WÁLÉ, O.: *Ìgbà Lonígbàá Kà*

10. Ṣàlàyé ohun tí akéwì sọ nípa "Gbájúẹ̀".

## ERÉ ONÍTÀN

ẸṢỌ́-OLÚBỌRỌ̀DÉ, S.: *Ìyàwó Aláréde̩*

11. Ṣàlàyé ohun tí alága sọ níbi ayẹyẹ tó tẹ̀lé ìgbéyàwó Mojèrè àti Ọládélé.

www.myschoolgist.com

## ÌPÍN D

## ÀṢÀ

[ 15 marks ]

*Dáhùn ìbéèrè* **kan ṣoṣo** *nínú ìpín yìí.*

12. Ṣàlàyé ìtọ́jú irun gẹ́gẹ́ bí ara aájò ẹwà ní ààrín àwọn Yorùbá.

13. *(a)* Kọ àpẹẹrẹ èèwọ̀ **márùn-ún**.

    *(b)* Ṣe àlàyé ìwúlò èèwọ̀ kọ̀ọ̀kan.